# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Ẹ SA AGBARA NYIN FUN ILU OGBOMOṢO

Olotu, jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ oloyinmọmọ, ak'ọmọ lọgbọn lati le jẹki iwe mi yi tete jade, lati sọ si etigbọ awọn ọmọ Ogbomọṣọ to wa nile ati nidalẹ.

Gẹgẹ bi iwe Mimọ ti wipe "awọn ọmọ de oju ibi, agbara ko si lati bi". Gẹgẹ bi ori ọrọ mi. Mo fi ṣedunẹdun kọwe yi lati bẹ awọn ọmọ Ogbomọṣọ to wa ni Oke-Okun, ati ni ilẹ Hausa (No thern Nigeria) si awọn ti Ọlọrun bukun ati awọn to jẹ ogunna gbongbo ti da'tọ lẹnu igbin, e ni awọn ti owo gidi mbẹ lọwọ wọn.

Bi awọn alagba wa yiti o wa ni Kumasi, Alagba Okewọle, J. J. Ọlọrunyọmi, Moses Agbojinmi, S. O. Ogunlọwọ ati awọn patakipataki miran ti emi ko le daruko nwọn tan bẹna si tun ni a le ri bakanna ni ilu Sekondi Takoradi bi awọn Alagba P D Onireti, S A Ladeji, S A Laleyẹ ati ni Tarkwa bakanna bi awọn Alagba Amusa Akanji ati ọpọlọpọ bakanna. Papa julọ ni Tamale bi awọn Alagba Alhaji Adisa Sarumi, Ni Prestea bi awọn Ṣitu Akande, Alagba James Arẹmu ati ni Accra pẹlu bi Alagba Ajao Dokita ati Alagba William ati ni Eko paapa bi awọn S A Oyelọwọ ati ni ilu kọkan ni ilẹ Nigeria na pẹlu, eyiti ko si aye lati ma daruko wọn lọṣọṣọ.

Ẹ jẹki a fi ti awọn Alagba wa yi ṣe apẹrẹ ni ilu Awẹ ati ni ilu Ọyan. Alagba J A Ajao nilu Awẹ ati Alagba J.O.B. nilu Ọyan fun iranlọwọ ti nwọn ti ṣe sinu ilu wọn eyiti ko ni i gbagbe lailai. Nitorina ki olukuluku ko ṣe gẹgẹ bi agbara rẹ ti to ki Olowo mura, ki talakagbiyanju lati wa ire ati igbega ilu wa Ogbomọṣọ.

Mo bẹ gbogbo ọmọ ilu Ogbomọṣọ lati fi ifẹ ilu wa han nipa ipade ti o ku si dẹdẹ yi. Mo fẹ ki o yẹ wa pe ogun jija ti awọn baba nla wa ti ja, ti nwọn si ti ṣẹgun pẹlu ibọn, ọfa olero ati ida ati pẹlu orisirisi nkan agbara miran. Fun idi eyi ni awa ọmọ wọn fi nri aye ṣe ogo loni, ṣugbọn ogun owo ni ti ode oni yi.

Ṣe gẹgẹ bi agbara ti Ọlọrun fi fun ọ fun igbega ilu Ogbomọṣọ, Olotu, abọ mi re o, ajinde ara yio ma jẹ fun nyin o.

Emi ni Ọmọ nyin
Sekondi Takoradi Area

P. O. Box 173
SEKONDI

## Ẹ LA EYI YE MI?

Inu mi yio dun pupọ ti Olotu ba le gba mi laye lati bere ọrọ yi lọwọ awọn ọjọgbọn onkawe Irohin Yoruba.

Ibere mi na ni wipe Baba kan wa, o fi ọmọ rẹ lọkọ gẹgẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ, ọmọ baba yi si bi mọ 'kunrin ati ọmọ'bir n fun ọkọ rẹ na.

Ni ọjọ kan ọkọ yi wa ana rẹ (baba iyawo rẹ) yi lọ. Ko si ba a ni ile ṣugbọn o gbọ ohun iyawo ana rẹ na ni iyara ti o sọ wipe ọkọ na ko si ni ile, ni ọkọ ọmọbirin baba si ba wọ iyara tọ iyawo baba iyawo rẹ lọ.

Ka ma fa ọrọ gun lọ titi mọ, baba iyawo rẹ na ka a mọ inu yara pẹlu obinrin rẹ o si mu u ki o jẹwọ pe on ṣe aina pẹlu obinrin na,

Nṣe ti baba iyawo na wa mọ nipa ọran yi, Kini ẹtọ rẹ lati ṣe Ọmọ rẹ ni ki o gba lọwọ ọkunrin na ni tabi iyawo rẹ ti ọkọ ọmọ rẹ wọle tọ na ni ki o le lọ? Tabi kini o tọ ki o ṣe?

Abọ mi re o.

Emi ni,
Kokumọ
"Enia ṣoro"

ABẸOKUTA.


# MA WU IKỌ MỌ



Bẹrẹ si ma a lo Veno's Cough Mixture lati isisiyi lọ, ki o si ri i bi yio ti da ikọ rẹ duro bi ọgan! O jẹ iwosan pataki fun ọna ọfun didun, otutu aiya ati arun jẹdọjẹdọ.

Tete ra igo kan nisisiyi!

THE IDEAL FAMILY REMEDY FOR COUGHS, COLDS, BRONCHITIS CATARRH, CATARRHAL ASTHMA CHEST COLDS, NIGHT COUGHS CHILDREN'S COUGHS.

VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE



## Ẹ ma a polowo Ọja nyin sinu iwe "IROHIN YORUBA"

Ẹ o si ri iyato larin bi a ti ti ni onibara si ati bi e o ti tan bere si ti ni si lati isisiyi lọ.



KO SI OTUTU MỌ



# MENTHOLATUM



O fẹrẹ jẹ pe ni ẹsẹkẹsẹ na ti o ba si lo "Mentholatum" n otutu ti nlọ. Fi si iho imu. Fi pa ọna-ọfun ati aiya. Bi o ba bẹrẹ si fa orun itura "Mentholatum" simu, ni gbogbo idọti agbari ati ti imu a ti bẹrẹ si i jade a si fun aiya ni alafia a ti tun mas mi daradara. Tete lọ ra idẹ tabi agolo "Mentholatum" kan loni. Fi pa aiya ki o si ti i bọ imu

Bere fun Mentholatum gan a. Eyi n jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est, 1889) Slough, England nikan ni wọn nṣe e



# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi— Iṣana orisirisi (Matches), Oogun Iya gbẹ, Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes), Leather Shoes (orisirisi), Beer, Shnapps, Gin, Wine, Brandy

# Medicine Stores

A tun nta awọn orisirisi ogun ni oke Ṣọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ọjọ-ṣe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati awọn 'un Obinrin ati Okunrin Sakaragbe, Ehin Ọmọde


## OGBOMỌSHỌ ṢE AJỌYỌ

ACCRA—Ni owurọ kutu ọjọ kẹfa oṣu kẹjọ ọdun yi ni awọn ọmọ Ogbomọṣọ ti o wa ni ilẹ yi ṣe ajọyọ Ẹsẹ gbogbo ọmọ Ogbomọsho ti pejọ si ile ajọ wọn, Olotu ọtọ ni ajọyọ awọn ọmọ Ogbomọsho ti Accra nitoripe awọn Ọlọpa alaṣọ-dudu meji ni awọn Ijọba yan fun wọn rigbati nwọn nṣere kiri Aria-ilu. Eyi fi han daju wipe Ọlọrun lọwọ si Ajọyọ na, nitoripe kosi ija kosi ita ti nwọn fi pari gbogbo ajọyọ na patapata.

Ẹ wa wo Amiẹu Balogun Ọlalẹyẹ ninu Doburu ẹwu Sanyan ati ẹwu Etu ca fo ko wọn lọ ti o si ko wọn bọ, a ki Alaga Joseph Popoọla, akọwe wa onilakaye Sam Orukọtan, a ki Yesufu Adeniyi eniti iṣe Alaga parapọ, Saka Ailara Oninure, Gbadamọsi Owolabi, William Arẹmu, Solomon Adeniyi Samuel Koje, Emm-Akanni Dafid Akinade Kobiou-enikan, Samuel Adisa James, T. Lalẹyẹ D. Oyelaran Oyekọla, Afọlabi.

Awọn Ewe pọ lara ọṣẹ, awọn obinrin wa ṣe ayọsi pupọ, Mercy Adefẹ, Safuratu Ayinkẹ, Dọja Omilana, a ki Adebisi Iya Ẹgbẹ, Duntan Iya-Ẹgbẹ Moranikẹ. A ki awọn onilu wa Ayangbula ati Lalokua. Ẹyin ọmọ Ogbomọ ko omitira na ko ni wọ nyin lọ

